# Èdè Yorùbá, Ọ̀rọ̀ Àyálò àti Ọ̀rọ̀ Àdàpọ̀, àti akẹ́kọ̀ọ́ kíkọ́ ní ìlú Amẹ́ríkà

Victor Tèmítọ́pẹ́ Àlàbí
Indiana University, Bloomington
vtalabi@indiana.edu

## Àsamọ̀

Èrò mi nínú àpilẹ̀kọ yìí dá lórí àwọn ọ̀rọ̀ àyálò nínú èdè Yorùbá nípasẹ̀ àjọṣepọ̀ tí ó tí wà láàrin èdè náà àti èdè Òyìnbó ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Mo ṣàlàyé wí pé èyí kì í ṣe tuntun rárá nítorí pé bá kan náà ni ọmọ ṣorí bí èdè méjì bá ní àjọṣepọ̀. Àpilẹ̀kọ náà mẹ́nu ba àwọn ìṣòro tí àwọn ọ̀rọ̀ àyálò wọ̀nyí lè dá sílẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè àkọ́kúnteni. Nípari, a gba àwọn olùkọ́ nímọ̀ràn lórí àwọn ọgbọ́n ìkọ́ni tí yóò wúlò púpọ̀ fún iṣẹ́ wọn.

## Ìfáàrà

Tí èdè méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ bá ní àjọṣẹpọ̀, yálà nípa ẹ̀sìn, ìdòwòpọ̀, tàbí ìjẹgàba ìlú kan lórí ìmíràn (Ajolore 1982), ó ma ń fa kí ọ̀rọ̀ àyálò kó jẹyọ láti inú èdè kan sí ìmíràn. Àwọn elédè a máa ní èdè kíní (ti abínibí) àti èdè kejì (tí wọ́n ti kọ́ tàbí tí wọ́n ń lò pẹ̀lú èdè kíní wọn). Àwọn elédè náà a máa yá ọ̀rọ̀ kan lò, láti èdè kan sí ìkejì, fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí, bí àpẹẹrẹ, láti ṣe àpèjúwe nǹkan nínú èdè kejì, tí kò sí nínú èdè kíní wọn. Bákan náà, tí a bá fẹ́ yá ọ̀rọ̀ kan lò, ọ̀rọ̀ yìí á ní láti tẹ̀lé ìlànà èdè tó ń yá ọ̀rọ̀ náà, fún àpẹẹrẹ, a yá "tábìlì" ("table") láti èdè Gẹ̀ẹ́sì, ṣùgbọ́n nítorí pé èdè Yorùbá kò fi ààyè gbà fún kí kọ́nsónáàntì méjì /b/ àti /l/, kí wọ́n wà lẹ́gbẹ̀ẹ́ ara wọn ni afi fi fáwẹ̀lì /i/ sí àárín wọn.

Lílo ọ̀rọ̀ àyálò wọ́pọ̀ kárí ayé láàárín àwọn èdè àgbáyé. Àyálò náà wọ́pọ̀ láàárín àwọn tí wọ́n ń lo èdè tó ju ìkan lọ. Nígbà míràn, oun tí èèyàn fẹ́ sọ léè ní ìtumọ̀ tí ó nípọn nínú èdè ìkejì tí kò sì rí bẹ́ẹ̀ ní èdè ìkíní, nítorínà, á pọn dandan láti yá ọ̀rọ̀ lò. Ọ̀rọ̀ àyálò léè jẹyọ nípasẹ̀ ìgbéyàwó láàárín elédè kan àti elédè míràn; tàbí látàri ìdòwò láàárín oníṣòwò elédè kan àti elédè míràn; tàbí tí elédè kan bá ń kàwé ní òkè òkun ti elédè míràn; tàbí tí elédè ìlú kan bá ń jọba lórí ìlú míràn. Irú nǹkan tí ó ṣẹlẹ̀ ní ìlú Nàìjíríyà nìyí nígbàtí èdè Gẹ̀ẹ́sì

wọlé sí ilẹ̀ Yorùbá. Ètò bébà yìí ni láti sọ̀rọ̀ nípa èdè Yorùbá; àjọṣepọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì àti ède Yorùbá àti ipa tí ó ní lóri èdè Yorùbá; àti ọ̀nà tí a fi lè mú kí kíkọ́ èdè Yorùbá kó sunwọ̀n si.

## Ọ̀rọ̀ ṣókí nípa èdè Yorùbá

Èdè Yorùbá jẹ́ ìkan lára àwọn èdè gbòókì ní ìlú Nàìjíríyà (ní ìwọ̀-oòrùn Áfíríkà). Àwọn ọmọ Yorùbá gbàgbọ́ pé Ilé-Ifẹ̀ ni orísun ọmọ Yorùbá. Ilé-Ifẹ̀ wà ní ìpínlẹ̀ Ọ̀sun. Àwọn ìpínlẹ̀ Yorùbá míràn ní ìlú Nàìjíríyà ni Ọ̀yọ́, Òndó, Ògùn, Èkó, Èkìtì, àti ní gúsù Kúwárà. Ẹ̀ka èdè Yorùbá ti Ọ̀yọ́ (Bámgbóṣé 1966) (bí ó ti lẹ̀ jẹ́pẹ́ àwọn ẹ̀ka èdè Ọ̀yọ́ míràn wà); ni wọ́n ń lò fún sísọ; àti fún kíkọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ìwé ní ilẹ̀ Yorùbá. Oun làá ń pè ní ojúlọ̀wọ́ èdè Yorùbá. Àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá míràn ni Ẹ̀gbá, Àkókó (àti àwọn ẹ̀ka wọn), Ìjẹ̀ṣà, Ìjẹ̀bú, Àkúrẹ́, Ìlàjẹ, Ọ̀wọ̀, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ (ẹ wo Adétugbọ̀ 1967, Adéníyì 2005). Yàtọ̀ sí ìlu Nàìjíríyà, àwọn elédè èdè Yorùbá wà ní àwọn orílẹ̀-èdè míràn ní ìwọ̀-oòrùn Áfíríkà, bíi ní Gánà, Tógò; àti ní àwọn agbègbè gúsù Amẹ́ríkà, bíi ní ìlú Bùràsílì, Kúbà, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìtàn (ẹ wo Falola 2006, Johnson 1921) sọ fún wa wípé àwọn amúnisìn ará ilẹ̀ Àpapọ̀ Ìjọba Gẹ̀ẹ́sì tí wọ́n ń sọ èdè Gẹ̀ẹ́sì, wá sí ìlú Nàìjíríyà ní ilẹ̀ Yorùbá ní ó lé ní ọgọ́rùnún ọdún sẹ́yìn. Àwọn amúnisìn náà mú ẹ̀sìn àti èdè Gẹ̀ẹ́sì wá (Johnson 2009). Nípa lílo èdè yìí, pàápàá fún ẹ̀kọ́ onírurú bíi nípa ìwé kíkà, ìwé kíkọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti jíjẹ́kí iṣẹ́ kó wà fún àwọn tó kàwé, ó wá pọn dandan kí àwọn ọ̀rọ̀ àyálò kó jẹyọ láti èdè Gẹ̀ẹ́sì sí èdè Yorùbá. Wọ́n wá tún dá ilé ẹ̀kọ́ gíga sílẹ̀ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ léè tẹ̀síwájú ìwé kíkà si, bíi nípa ẹ̀kọ́ ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìmọ̀-ìjìnlẹ̀, ìmọ̀-iṣòwò, ìmọ̀-agbẹjọ́rọ̀, àti bẹ́ẹ̀ lọ, èyí tún dá kún ọ̀rọ̀ àyálò lílò. Yàtọ̀ sí èdè Gẹ̀ẹ́sì, àwọn ọ̀nà míràn, bí a ṣe ti sọ níwájú, bíi títà àti rírà lááárín àwọn oníṣòwò ilẹ̀ Yorùbá àti àwọn ilẹ̀ míràn bí àwọn ilẹ̀ Haúsá náà mú ọ̀rọ̀ àyálò wá sí inú èdè Yorùbá.

Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa Yorùbá bíi Bámgbóṣé (1966), Bámgbóṣé (1986), Awóbùbúlì (2001) Adéníyì & Òjó (2005) àti bẹ́ẹ̀ lọ, ti ṣàlàyé ìyípadà èdè Yorùbá nítorí èdè Yorùbá tí à ń lò lóde òní kọ́ ni àwọn babańlá wa lò láyé àtijọ́. Àyípada ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló ti dé bá ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá láti ẹyọ-ọ̀rọ̀ dé gbólóhùn, fún àpẹẹrẹ lórí àwọn ọ̀rọ̀ sísọ bíi "aiyé", "ẹiyẹ", "lí òkè"; àti ọ̀rọ̀ kíkọ bíi "Òshogbo", "Ìddó" (ẹ wo Adéníyì & Òjó 2005); Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ odún sẹ́yìn, kí èdè Gẹ̀ẹ́sì tó wọ ilẹ̀ Yorùbá, àwọn Yorùbá ní ọ̀rọ̀ fún gbogbo nǹkan tí wọn ń lò, tó jẹ́ pé ọ̀rọ̀ náà ní ṣe pẹ̀lú ìtàn, àṣà, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá. Nígbà míràn, ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ kan á ní ìdí kan tí a lè rí nínú ìtàn. Ọ̀rọ̀ bíi àga, ife, ìwé, àpótí, àpò, olubi, ajá, òkété, ìgbá, igi, ọkọ̀, ibùnsùn, abúlé, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ, ní nǹkan tí wọn tọ́ka sí; wọ́n sì ní orísun ìdí tí wọn fi ń jẹ́ ọ̀rọ̀ tí wọ́n ń jẹ́. Ní òde òní tó jẹ́ ayé ọ̀làjú, a wá ní òríṣìí àga, òríṣìí àpò, òríṣìí ibùnsùn, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Láti lè júwèé nǹkan pàtọ́, ó wá ṣe pàtàkì láti yá ọ̀rọ̀ wọ èdè Yorùbá.

## Ọ̀rọ̀ Àyálò àti Ọ̀rọ̀ Àdàpọ̀

Nítorí àwọn nǹkan tí a mọ̀ ní òde òní, tí kò sí ọ̀rọ̀ nípa wọn ní èdè Yorùbá ní àtijọ́, ni a fi ní ọ̀rọ̀ àyálò, bí àpẹẹrẹ: rédíò, tẹlifóònù, kápẹ̀tì, kọ̀mpútà, pẹ́ẹ̀nì, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Nitorí náà, tí a kò bá ní ọ̀rọ̀ láti ṣe àpèjúwe nǹkan nínú èdè kan, a má ń yá ọ̀rọ̀ láti èdè ìmíràn, pàápàá tí àwọn tí wọ́n ń lo èdè náà bá ní agbára láti lo èdè méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí kò burú rárá nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè àgbáyé ló ní onírurú ọ̀rọ̀ àyálò láti èdè míràn.

Ní òde-òní, àwọn Yorùbá pàápàá àwọn tí wọn ń gbé ní ìlú Nàìjíríyà ma ń lo àdàpọ̀ Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì tí wọ́n bá ń sọ̀rọ̀. Èyí wọ́pọ̀ láàárin àwọn tí wọ́n kàwé àti àwọn tí wọn kò kàwé. Ipa èyí kò sì dára fún èdè Yorùbá láàárín àwọn Yorùbá pàápàá àwọn ọmọdé ní ìlú Nàìjíríyà. Àpẹẹrẹ: "Mo ra *I-Pad* ní àná", "Ọ̀rẹ́ bàbá mi jẹ́ *Physiologist*", "Ko *take care*", àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Òótọ́ ni pé a kò ní gbogbo ọ̀rọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì nínú èdè Yorùbá, ṣùgbọ́n ó léwu láti tẹ̀síwájú pẹ̀lú àdàpọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì tí a bá gbọ́ àti èdè Yorùbá, nitorí pé ó má a fa ikú òjijì fún èdè Yorùbá.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn fíìmù Yorùbá ní ilẹ̀ Yorùbá ní àdàpọ̀ Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì. Ó wọ́pọ̀ débipẹ́ àwọn òṣèré eré Yorùbá a má a sọ ọ̀rọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì nígbà tí ẹ̀da rẹ̀ wà ní èdè Yorùbá tí wọ́n lè sọ. Nípa bẹ́ẹ̀, èdè Yorùbá wá ń kú lọ. Oun ìyàlẹ́nu ni pé àtúmọ̀ èdè máa fara hàn lóri ẹ̀rọ móhùn-máwòrán, ṣùgbọ́n àwọn òṣèré yìí á ṣì máa lo àdàpọ̀ èdè Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì, bí àpẹẹrẹ nínú eré: *Ìyàwo fìdí hẹ* láti ọwọ́ Wálé Ògúns. Àwọn òṣèré eré náà lo àdàpọ̀ ọ̀rọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì àti èdè Yorùbá papọ̀. Mo kọ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ṣeé lò, tí wọn kò bá lò, sínú ààmì-àkópò. Àwọn ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì tí àwọn òṣèré náà lò ni a kùn ní dúdú. Ọ̀rọ̀ yìí wáyé láàárin ọkùnrin kan àti àfẹ́sọ́nà rẹ̀.

> **Afterall** titìẹ náà ni mò ń ṣe... (Pẹ̀lú-pẹ̀lú)
> Má **ever** sọ fún mi pé titìmi náà ni ò ń ṣe... (láíláí)
> Láti lọ wá máa **frame** irọ́... (ṣètò)
> ọ̀gá ẹ ṣẹ máa wá **invite**... (pè)
> ẹ ti **believe**... (gbàgbọ́)
> Fún mi ní **information**...(ìròyìn)
> O ní ki n **trust** ẹ... (gbẹ́kẹ̀ lé)

Tí àwa ọmọ Yorùbá tàbí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá fún àpẹẹrẹ, bá ń wo àwọn eré wọ̀nyí, kò le ran gbogbo wa lọ́wọ́ rárá. Ó ṣe ni ní kàyéfì pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn eré Yorùbá tí ó wà lórí ẹ̀rọ yútubù ni àwọn òṣèré ti lo àdàpọ̀ Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì. Nínú iṣẹ́ kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ìlú Amẹ́ríkà ní Yorùbá, àwa olùkọ́ maá ń lo oun tí à ń pè ní àwọn oun èlò ojúlówó láti kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ìlú Amẹ́ríkà, bíi fíìmù, àwòrán, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ, nípa àṣà Yorùbá. Ó wá ṣoro láti lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn fíìmù bẹ́ẹ̀ láti fi kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Tí àwa ọmọ Yorùbá tàbí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá bá ń wo àwọn eré wọ̀nyí, kò lè ran ìdàgbàsókè èdè Yorùbá lọ́wọ́ rárá.

Nítorí náà àwọn ọmọ Yorùbá tí wọ́n ń sọ èdè Yorùbá àti èdè Gẹ̀ẹ́sì a má a yá ọ̀rọ̀ lò tàbí da ọ̀rọ̀ pọ̀. Yàtọ̀ sí èdè Gẹ̀ẹ́sì, àwọn èdè míràn tí a ní àyálò sí èdè Yorùbá ni èdè Àrábìkì bí àpẹẹrẹ: àlùmọ́nì, àlùbáríkà, àṣírí, bìlísì, fìtílà, rìbá, wàhálà, sàkánì, ṣìná, wàásù, (Abdul 1976) àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. A ní ọ̀rọ̀ àyálò láti èdè Haúsá náà bí àpẹẹrẹ: làbárì, àlùbọ́sà, (Abdul 1976) àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ ṣùgbọ́n èdè Yorùbá ní ọ̀rọ̀ àyálò púpọ̀ láti èdè Gẹ̀ẹ́sì nítori odún púpọ̀ tí èdè Gẹ̀ẹ́sì àti èdè Yorùbá ti jọ wà pọ̀.

Lílo ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ Yorùbá kò wọ́pọ̀ láàárin àwọn ọ̀dọ́ ọmọ Yorùbá mọ́ ní òde òní. Ìdí abájọ tí Fábùnmi & Sàláwù (2005) ṣe sọ pé ìwùwàsí ọmọ Yorùbá kù díẹ̀ káàtó sí èdè Yorùbá. Balógun (2013) náà sọ pé èdè Yorùbá ń kú lọ díẹ̀ díẹ̀. Nítorí náà, yàtọ̀ sí pé à ń lo ọ̀rọ̀ àyálọ̀ bíi "tábìlì", "kọ́bọ̀dù", "fírìjì", àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ, tí kò burú rárá, a ní lò láti ṣètò fún àwọn ọ̀rọ̀ tuntun yálà ọ̀rọ̀-ọlọ́rọ̀ kan (ilé), ọ̀rọ̀-ọlọ́rọ̀ méjì (ilé-túbú), ọ̀rọ̀-ọlọ́rọ̀ mẹ́ta (ilé ìfowó-pamọ́); tàbí ọ̀rọ̀ láti ìtàn, àṣà, ní Yorùbá. Tí àwa elédè èdè Yorùbá kò bá múra sí lílò ojúlówó èdè Yorùbá ní ìgbàkúùgbà, yóò lọlẹ̀ gidigidi láti: Àyálò sí Àdàpọ̀ sí Àìlèsọ sí Àìlègbọ́ sí Àìmọ̀. Ó ṣe pàtàkì kí a dín ọ̀rọ̀ àdàpọ̀ kù. Ó yẹ kí a gbìyànjú láti má a sọ̀rọ̀ fún ìṣẹ́jú mẹ́wàá, mẹ́ẹ̀dógún, láì lo àdàpọ̀ èdè Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì.

Ní abúlé àti ní ìgbèríko, àwọn àgbà àti ọmọdé ṣì ma ń sọ èdè Yorùbá dáadáa ṣùgbọ́n gbígbé ní ìlú ní ipa tí ó ń kó láti má jẹ́ kí sísọ èdè Yorùbá kí ó gòkè. Púpọ̀ nínu àwọn ọmọ Yorùbá tí wọ́n jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti girama aládáni tí mo bá pàdé ni wọn kò fẹ́ràn láti máa sọ èdè Yorùbá, ṣùgbọ́n wọ́n gbọ́ èdè náà. Púpọ̀ nínu wọn gbàgbọ́ pé lílo èdè Gẹ̀ẹ́sì máa fún wọn ní àǹfàní àwọn oun mère-mère ju èdè Yorùbá lọ. Nínú ìwádìí mi, mo ri pé ó ṣòro kí àwọn ọmọ Yorùbá ilé-ẹ̀kọ́ girama àti ilé-ẹ̀kọ́ gíga (ní ìlú Nàìjíríyà àti ọmọ Yorùbá tó ti pẹ́ ní ìlú Amẹ́ríkà) sọ ọ̀rọ̀ Yorùbá fún ìṣẹ́jú máàrúnúndínlógún láì lo àdàpọ̀ Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì.

## Kíkọ́ Àwọn Akẹ́kọ̀ọ́ ní ìlú Amẹ́ríkà

Èdè Yorùbá ti gbilẹ̀ sí ìlú Amẹ́ríkà débipé ìpínlẹ̀ ó lé ní ogun ni wọ́n ti ń kọ́ èdè Yorùbá. Ó wá pọn dandan láti ri pé a ṣètò láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ fún àwọn oun tuntun tí àwọn òyìnbó ń ṣẹ̀dá. Tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá bi wá pé kíni ìtumọ̀ nǹkan tèyí àti tọ̀ún, ó máa dára láti dáhùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tuntun tí kò ní àdàpọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì kankan gẹ́gẹ́ bíi orísun. Èyí lè jẹ́kí wọ́n bèèrè ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ náà, kí a lè wá sọ̀rọ̀ nípa orísun rẹ̀ ní èdè Yorùbá.

Ó yẹ kí àwa ọmọ Yorùbá dìde láti ṣètò bí a ṣe lè ṣèdá àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tí ó máa fi ìtàn, ìgbàgbọ́, àṣà, ìṣe, àwọn Yorùbá hàn kí a lè rí nǹkan sọ nípa àṣà Yorùbá, fún àpẹẹrẹ, tí a bá fẹ́ sọ̀rọ̀ nípa orísun ọ̀rọ̀ kan. Àwa olùkọ́ Yorùbá ní ìlú Amẹ́ríkà nílò láti lóòrèkóòrè má a kọ bébà tàbí ìwé nípa àwọn nǹkan tuntun tí à ń gbọ́, tí à n rí, tí wọ́n ní ìtumọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì, kí a wá ìtumọ̀ èdè Yorùbá fún wọn, tí kò ni jẹ́ pé a kàn fi fáwẹ́ẹ̀lì díẹ̀ sí ara ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì.

Ó ṣe pàtàkì láti jẹ́ kí èdè Yorùbá kó gbilẹ̀ si. Gẹ́gẹ́ bí Adéèboyèjẹ́ (1985) ṣe sọ, èdè jẹ́ oun ẹlẹ́mìí tí ó lè gbèrú, tàbí tí ó lè kú. Nípa èdè, Adéèboyèjẹ́ (1985:3) sọ pé "tí a bá tọ́jú rẹ̀ dáadáa nípa títan sísọ, kíkà àti kíkọ rẹ̀ káàkiri àti nípa yíyá ọ̀rọ̀ àjèjì wọ inú rẹ̀ ni ó máa ń dàgbà sókè". Ó dára láti yá èdè, ṣùgbọ́n ó ṣe pàtàkì pé àwọn onímọ̀ èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ ṣètò bí àwọn ọ̀rọ̀ èdè Yorùbá tó jẹ mọ́ àṣà ṣe lè wọlé sínú èdè Yorùbá. Àwọn ọ̀nà díẹ̀ tí a lè gbà àti tí a lè tẹra mọ́ níwọ̀yí pàápàá ní ìlú Amẹ́ríkà:

(1) Lílò àti kíkọ́ akẹ́kọ̀ọ́ nípa òwe, àkànlò èdè àti àwọn èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá lóòrèkóòrè;
(2) Ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ nípa àwọn ẹ̀yà ara àti bí a ṣe lè lò wọ́n pẹ̀lú orúkọ nǹkàn àyíká nílẹ̀ Yorùbá (ẹ wo Dingemanse 2006) bí àpẹẹrẹ: "**ojú-ọ̀nà**", "**ẹnu-ọ̀nà**", "**etí-òkun**", "**ìdí-ọkọ̀**", "**ẹsẹ̀-òkè**";
(3) Kí àwọn òṣèré eré Yorùbá kọ̀ láti máa lo àdàpọ̀ èdè Yorùbá àti Gẹ̀ẹ́sì nítorí fífi eré fíìmù kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́;
(4) Kíkọ́ oníruru orin nipa àṣà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́;
(5) Lílo àti kíkọ́ nípasẹ̀ ìtàn;
(6) Lílò àti kíkọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní eré ìdárayá, bíi "bojú-bojú";
(7) Kíka àwọn ìwé ìtàn, ìwé ewì, àti ìwé nípa eré;
(8) Kíkọ́ nípa ìtàn nípa àwọn olórí ńlá ní ilẹ̀ Yorùbá bíi Ọbàtálá, Ṣàngó;
(9) Láti lo ìròyìn láti orí ẹ̀rọ asọ̀rọ̀-mágbẹ̀sì láti fi kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́;
(10) Lílo àwọn ọ̀rọ̀ titun tí àwọn atẹ̀wé ń lò, láti gbé èdè Yorùbá láruge;
(11) Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa gbìyànjú láti máa sọ èdè Yorùbá láì ṣe àdàpọ̀ pẹ̀lú Gẹ̀ẹ́sì;
(12) Kíkọ ìwé ìtumọ̀-èdè nípa ọ̀rọ̀ méjì, tàbí mẹ́ta tí ó ní ìtumọ̀ kan;
(13) Kíkọ ìwé ìtumọ̀-èdè pàtó nípa orúkọ èèyàn, nípa ẹyẹ, nípa oúnjẹ, nípa àwọn ìlú ilẹ̀ Yorùbá; àti
(14) Fífi àwọn oun èlò nípa èdè Yorùbá sí orí ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá, kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ léè lò wọ́n.

## Ọ̀rọ̀ Ìparí

Ó ṣe pàtàkì láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ púpọ̀ sílẹ̀ fún èdè Yorùbá nítorí a ti ní oríṣìí àga, oríṣìí ẹlẹ́rìn-dòdò, ẹ̀rọ, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Lóde òní, àwọn elédè Yorùbá fẹ́ lo ọ̀rọ̀ pàtọ́ fún nǹkan pàtó, fún àpẹẹrẹ: ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹlẹ́rìn-dòdò ló wà. Láti yá ọ̀rọ̀ lò bíi fáńtà, kóòkì, kò burú ṣùgbọ́n ó lè léwu láti tẹ̀síwájú nínú iṣẹ́ yíyá gbogbo ọ̀rọ̀ tí a kò ní lédè Yorùbá.

## Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí

Abdul, M.A. "Arabic Loan Words in Yorùbá." Yoruba. 2 (1976): 37–42.

Adéèboyèjẹ́, Adé. *Èdè àti Gírámà Yorùbá*. Lagos: Macmillan, 1985.

Adéníyì, Harrison and Akinloyè Òjó, eds. *Ìlò Èdè àti Ẹ̀dá-Èdè Yorùbá. Ìwé kejì*. Trenton: Africa World Press, 2005.

Adéníyì, Harrison. "Àwọn Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá." In *Ìlò Èdè àti Ẹ̀dá-Èdè Yorùbá*, eds. Harrison Adéníyì and Akinloyè Òjó, 23–54. Trenton (USA): Africa World Press, 2005.

Adetugbo, Abiodun. "The Yoruba Language in Western Nigeria: Its Major Dialect Areas." Unpublished doctoral dissertation, Columbia University, New York (USA), 1967.

Ajolore, Olúsọlá. "Lexical Borrowing in Yoruba." In *Yoruba Language and Literature*, ed. Adebisi Afọlayan, 145–164. Ilé-Ifẹ̀ (Nigeria): University of Ifẹ Press, 1982.

Awóbùbúlì, O. "Ìtàn Èdè Yorùbá." In *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá*, ed. Bádé Àjàyí, 8–28. Ìlorin (Nigeria): Unilorin Department of Linguistics and Nigerian Languges, 2001.

Balogun, Temitope Abiodun. "An Endangered Nigerian Indegenous Language: The Case of Yorùbá Language." *African Nebula*. 6 (2013): 70–82.

Bámgbóṣé, A. *A Grammar of Yoruba*. Cambridge: Cambridge UniversityPress, 1966.

Bámgbóṣé, A. *Yorùbá: A Language in Transition*. Lagos: Ọdúnjọ Memorial Lectures Organising Committee, 1986.

Dingemanse, Mark. "The Body in Yoruba: A Linguistic Study." Unpublished Master's Thesis, Leiden University, Leiden (Netherlands), 2006.

Fabunmi, Felix A. and Akeem Salawu. "Is Yoruba an Endangered Language?" *Nordic Journal of African Studies*. 14.3 (2005): 391–408.

Falola, Toyin. "The Yoruba Nation." In *Yorùbá Identity and Power Politics*, ed. Toyin Falola and Ann Genova, 29–48. Rochester (USA): University of Rochester Press, 2006.

Johnson, Samuel. *The History of the Yorubas*. Lagos: CSS Bookshops, 1921.